# OFIN OMINIRA IWIFUN TI ODUN 2011

RIGHT TO KNOW

**Pelu awosopo**

OPEN SOCIETY INITIATIVE FOR WEST AFRICA

# OFIN OMINIRA IWIFUN TI ODUN 2011

Ofin lati je ki iwe iranti ati iwifun rorun lati ri, paapaa ti o ba wa fun awujo ati fun iwifun awujo ti o si je fun anfaani ati idaabo bo ara ilu, ti ko pa ominira enikeji lara, ti o daabo bo osise ijoba kuro ninu ewu nigba ti o ba se iwifun lai gba ase bi a ti fi le le lerongba ati se aseyori nnkan won-an-ni ti a ti la kale

## OFIN OMINIRA IWIFUN TI ODUN 2011

## ITO LESEESE

**IPIN SI ISORI:**


(1) Aaye si iwe iranti
(2) Iwifun nipa Awujo
(3) Ibeere fun iwe iranti
(4) Akoko fun gbigba tabi kiko ibeere
(5) Fifi iwe ibeere ranse
(6) Sisun akoko lati gba ibeere tabi lati sun ibeere siwaju
(7) Nigba ti a ba ko lati se iwifun tabi fi iwe-iranti sile
(8) Ibule owo (fees)
(9) Bi a se n fi iwe iranti pamo ati bi a se n toju re
(10) Bibaje tabi sise alupayida
(11) Imukuro nnkan ti o je mo orile ede agbaye ati aabo
(12) Imukuro awon agbofinro ati asewadi
(13) Kiko awon osise ni ona si eto lati mo iwifun ati imulo ofin yii
(14) Imukuro iwifun oro ara-eni
(15) Imukuro iwifun oro elomiran
(16) Imukuro anfaani ara eni tabi anfaani miran ti a ni labe ofin
(17) Imukuro awon nnkan elo iwadii
(18) Eyikeyii
(19) Kiko Ile ise ijoba lati fi iwe iranti han ni
(20) Ayewo ile-ejo
(21) Gbigbo ni soki (kukuru)
(22) Bi iwifun se le wa ni arowoto ile ejo
(23) Bi ile-ejo ko se ni tako iwifun
(24) Ase lati se iwifun
(25) Awon nnkan ti a yo kuro
(26) Didaabo bo osise ijoba
(27) Iwe ti a ya soto
(28) Ijabo ise
(29) Ona Igbekale
(30) Atupale
(32) Ifisori/ayolo

# OFIN OMINIRA IWIFUN TI ODUN 2011

## AKOKO AGOGO - FUN

Ofin lati je ki iwe iranti ati iwifun rorun lati ri, paapaa ti o ba wa fun awujo ati fun iwifun awujo ti o si je fun anfaani ati idaabo bo ara ilu, ti ko pa ominira enikeji lara, ti o daabo bo osise ijoba kuro ninu ewu nigba ti o ba se iwifun lai gba ase bi a ti fi le le lerongba ati se aseyori nnkan won-an-ni ti a ti la kale

(Ibere)

ISODOFIN: Lati owo ile igbimo asofin orile edeNigeria –

1. (1) Laisi ani-ani, nnkan ki nnkan ti o le wa ni nu ofin tabi ilana kan, eto

enikeni lati ni aaye si iwifun yala eyi ti a ko sile, ti o ba wa lowo osise ijoba ni ile isekise ti a lee juwe, ni a ti fi idi re mule.

(2) Onibeere labe ofin yi ko nilo lati so ohun ti o fe fi “iwifun se”.

(3) Enikeni ti o ba ni eto si iwe yii labe ofin yi, yoo leto lati le lo si ile ejo ki ile-ise ijoba lee se ohun ti ofin yii so.

2. (1) Ile ise ijoba gbodo rii pe won pa iwe iranti won mo daradara ki

gbogbo iwifun nipa ise, ise ati imulo won si kun regi - regi.

(2) Ile ise ijoba gbodo rii pe won se akojopo “iwifun” won daradara lona to je pe awon ara ilu yoo lee ni anfaani lati rii loore-koore.

(3) Ile ise ijoba yoo maa se atejade nnkan wonyi gege bi a se ko si itunpin si sori kerin ti isori yii:

(a) apejuwe ile-ise ati ise ile ise naa pelu ekunrere alaye nipa alakale ise elekajeka ile ise ohun.

(b) Awon oro wonyi:

i) Awon akosile ti o wa labe akoso ile ise ni kikun to bee ge ti yio fi se ranwo fun eto si iwifun labe ofi, ati

ii) Awon iwe itonisona ti awon osise ile ise nlo lati sakoso tabi

lati sagbejade eyi keyi lara awon eto tabi awon ise ti ile ise naa nse;

(d) alaye awon akosile ti o ni awon arongba ipari titikan erongba ti a faramo ati eyi ti a ko faramo bee gege ni ti ase ti a pa lori iyanju awon ejo;

(e) awon akosile ti o ni;

( i) ojulowo ofi ile ise.

(ii) Alakale ati itumo ise ti ile ise ti yan

(iii) Ise wa lori eto ikehin, awon ifisiwaju ati awon ifenuko,

(iv) Irohin oojo, irohin abewo ati ikeko yala eyi ti ile ise gbe kale fun ise,

(v) Iwifun ti o je mo igbowo wole tabi nina owo ilu tabi awon owo miran ti o je ti ile ise,

(vi) Oruko, owo osu, apeje ipo ati ojo igbanisise gbogbo osise ati awon oga ile ise,

(vii) Awon eto ijoba, ile ise ijoba tabi awon eniyan aladani

(viii) Oruko gbogbo awon alakoso ati akosile ipari fun idibo ati bi eto idibo se lo ni ile ise

(ẹ) ito leseese:

(i) awon faili ti a ko iwe ibere fun agbase ise, iwe ase, iwe owo iranwo, iwe irina tabi iwe adehun.

(ii) irohin, akosile, ikeko tabi iwe agbejade ti awon agbasese ti o daduro ko fun ile ise ati

(iii) awon ohun elo ti o kun fun iwifun lori owo iranwo tabi ise agbase ti ile ise se tabi laarin ile ise tabi aladani.

(f) ipo ati adiresi osise ile ise naa ti a le ko iwe ibeere si fun iwifun ti o si je pe atejade iwifun ile ise naa ko ni se aibofinmu fun awon ara ilu ti o nilo iwifun iru ile ise bee.

(4) Ile ise ijoba gbudo rii pe iwifun ti a so labe isori yii je eyi ti a polongo ti ara ilu si lee ri yala nipa kika, nipa imo-ero tabi ti ayelujara.

(5) Ile ise ijoba gbodo rii pe won n se atunyewo iwifun ti o ye lati te jade ni isori yii lore-koore, nigba ti ayipada ba de.

(6) Enikeni ti o ba ni eto labe ofin yii lati lo si ile ejo ki ile ise ijoba le se ohun ti ofin yi so.

(7) Ile ise ti a gbekale fun gbogbo eniyan tabi awon alase yala awon ti n se ijoba, asofin tabi awon amofin tabi ile ise ijoba, eka ile-ise tabi awon ajo miiran ti ijoba ni ase le lori tabi ile-ise miiran ti o n lo owo ijoba, ti o n se itoju awujo tabi ti o n se ise iluu.

3. ( 1) Iwe ibeere fun iwe iranti tabi iwifun ni isori yii yoo wa ni ibamu pelu isori kinni ofin yii.

(2) Ni ti ofin yii, gbogbo iwifun tabi iwe iranti ti a ba beere fun labe ofin yii ti a ko ba te jade sugbon gege bi ilana ti a le mu jade lenu ero ti ijoba n lo tabi ile-ise ijoba ni a o kaa si iwe iranti ijoba tabi ile ise ijoba.

(3) Eni ti ko mooko-mooka tabi alaabo ara ti o je pe ipo ti won wa ko lee je ki won beere fun iwifun gege bi a ti gbe kale ninu atun pin sisori (1) le se ibeere re nipa elomiran.

(4). Alase, osise ijoba tabi ile ise ijoba ti aba fi enu beere iwe iranti tabi iwifun lowo re yoo koo sile gege bi o ti wa ni ipin si isori (1) ti isori yii yoo si fun olubeere ni eda akosile bee.

4. Ibikibi ti a ba ti beere fun iwifun ninu ofin yii, ile-ise ijoba ti a ba se ibeere si yoo se. awon nnkan yii gege bi a ti ko ni isori kefa, ikeje ati ikejo ofin yii laarin ojo meje ti o ba gba iwe ibeere naa:

(a) fifun onibeere ni iwifun ti o beere fun;

(b) ti ile ise ijoba ba ri wipe ko ye ki a da onibeere lohun nipa ibeere re, yoo ko iwe lati salaye idi ti o fi ri bee ati abala ofin yii ti o so bee.

5. (1) Nigba ti ile-ise ijoba ba gba iwe ibeere lati odo enikan sugbon ti o rii wipe ile-ise ijoba miiran ni anfaani si iwifun naa ju ti oun lo yoo fi iwe ibeere naa ranse si ile-ise ti o ni anfaani juu lo laarin ojo meta si meje, si ojo ti o gba iwe ibeere naa, yoo si ko iwe si onibeere lati fi igbese re yii too leti, ninu eyi ti yoo ti salaye pe ile ejo lee se atunyewo ipinnu lati fi iwe ibeere naa ranse.

(2) Nigba ti a ba fi iwe ibeere ranse bi a se so ni atun pin si isori kinni yoo ja si pe a fi iwe naa ranse ni ojo ti ile ise ti a fi ranse si rii gba.

(3) Nitori atun pin si isori kinni, ile-ise ijoba ni "ife" si iwifun ti :

(a) a ba se atejade iwifun ohun ni ile-ise ijoba naa tabi fun ile-ise tabi
(b) ni ti iwifun ti a ko pile re ni ile ise ijoba, sugbon ti ile ise naa ni yoo je akoko ile ise ijoba lati gba iwifun ohun

6. Ile ise ijoba lee sun akoko ti a so ni isori karun tabi ikefa siwaju sugbon ko gbodo ju ojo meje ayaafi bi:

(a) iwe ibeere naa da le iwe iranti ti o po ti o si je pe ati se ise naa ni akoko ti a da labe ofin lee di ile ise naa duro lati se ise tiwon tabi ti o je pe ki a to le dahun ibeere naa a gbodo ri tabi se awon

(b) nnkankan ti o le mu ki a koja akoko ti a da labe ofin, sugbon ti a se ikilo ati sun ejo siwaju ninu eyi ti olubeere ni eto lati lo si ile-ejo fun isun si waju.

7. (1) Nigba ti ile ise ijoba ba ko lati fun olubeere ni iwifun tabi iwe iranti ti a beere fun labe ofin yii tabi abala iwifun tabi iwe-iranti, yoo se alaye idi abajo, ati abala ti o toka si sise bee labe ofin yii ati pe olubeere ni eto lati lo si ile ejo.

(2) Iwe yii ko dahunsi ibeere fun iwifun tabi iwe-ranti yoo so oruko, ipo ati ifowosi eni ti o ko lati dahun ibeere.

(3) Ijoba tabi ile ise ijoba yoo so labe atunpin si isori (kinni) isori yi boya iwifun tabi iwe-iranti naa wa.

(4) Nigba ti ijoba tabi ile ise ijoba ba fariga lati je ki awon eniyan ni anfaani si iwifun tabi iwe-iranti tabi die lara iwifun ti a beere fun labe ofin yii ni iye ojo ti a ko labe ofin yii, yoo tumo si pe ile-ise ijoba naa ko lati je ki awon eniyan ni anfaani si iwe-iranti ati iwifun.

(5) Nigba ti a ba fiidi aito re mule pe osise kan tabi ile-ise kan jebi nipa aije ki eniyan ni anfaani si iwifun tabi iwe-iranti, yoo san owo egberun lona eedegbeta Naira (₦500,000.00).

8. Owo sisan ko ni koja iye owo iseda-iwe ati owo awoko ti a nmulo lawujo.

9. (1) Gbogbo ijoba tabi ile-ise ijoba gbudo rii wipe won se abojuto iwe-iranti ati iwifun nipa ile ise won, ise won, awon osise won ati gbogbo ohun ti o jo mo iwifun ati iwe-iranti patapata.

(2) Gbogbo ijoba tabi ile ise ijoba gbodo rii wipe won toju iwifun ile ise won lona ti yoo fi rorun fun arowoto ara ilu.

10. O je ese ati iwa odaran ti ile ejo le jeni niya fun labe ofineyi to o kere ju funewon odun kan ti osise olori eka ile-ise ijoba kan ti o wa labe ofin yii ya tabi ba iwe-iranti ti o wa ni akoso re je tabi ki o pa nkankan re tabi ki o yi iwe naa ki o to di pe o fun olubeere tabi awujo.

11. (1) Ile ise ijoba lee ko lati dahun ibeere fun iwifun ti o ba rii pe o lee se ipalara fun ajumosepo laarin awon orile ede tabi orile ede Naijiiria.

(2) Laisi-ani-ani si itun pin si sori (kinni) a lee sai ko ibeere fun iwifun ti a ba rii pe anfaani ara ilu lori iwifun yii po ju ijamba ti iwifun naa lee se.

12. (1) Ile ise Ijoba lee ko ibeere fun iwifun ti o ba ni:

(a) sise pelu iwe-iranti ti ile ise agbofinro ijoba, ti o si wa fun eto ara won, ti o si jasi pe gbigbee jade lee ja si:

(i) sise ayojusi igbejo ti o n lo lowo ti ile ise agbofinro tabi eka re n se amojuto,

(ii) sise ayojusi eto ajo agbofinro ti ile ise ijoba n se,
(iii) se idiwo fun eniyan lati ni igbejo ododo tabi igbejo ti ko ni ojusaju
(iv) ti yoo pon dandan re fun lati fi ori sun asiri ijoba han,
(v) Ti ko ni ta ko ominira eda gege bi a ti gbe kale ni isori keedogun ofin yii, ayafi ti anfaani ara ilu ba se pataki ju ti eeyan kan ti a ba fi iru iwifun bee han,
(vi) sise idiwo fun iwadi odaran ti o n lo lowo; ati

(b) sise iwifun ti ole je idenaa si aabo ile-ise isedajo

(2) Bi o ti wu ki o ri, bi o se wa labe isori yii a ko ni se alaida onibeere fun iwifun lohun niwon igba ti ipa kika ara ilu ba ju ijamba ti iwifun naa lee se lo.

(3) Ile ise ijoba lee ko ibeere fun iwifun ti o ba lee fa ki awon eniyan maa huwa odaran.

(4) Nitori isori (kinni) (a) "Igbejoro igbofinro" tumo si iwadi ti:

(a) o ba je mo isemulo tabi amuse ofin tabi ilana kan.

(b) ofin tabi ilana kan fi aye gba.

13. Ijoba tabi ile ise ijoba gbodo ni idanileko fun awon osise won nipa eto eniyan si iwifun ati iwe-iranti ile ise ijoba ti a gbe kale labe ofin yi ati fun imulo ofin naa.

14 (1) Gege bi a ti gbe kale ni ipin si isori keji (2) ile ise ijoba gbodo ko ibeere lori

iwifun ti o ro mo ara eni ati iwifun ti a ya soto labe ipin si isori yii ninu eyi ti:

(a) faili ati iwifun ti a pamo fun ara eni, onibara eni, eni ti a n toju, olubagbe, akekoo, tabi elomiran ti o n gba iwosan, idanileko,isuna, ibojuto, tabi ise ti o ro mo ile ise ijoba yala ni taarata tabi idakeji;

(b) faili awon osise ati faili iwifun ara eni ti a n bojuto ti o je mo ti awon osise, awon ti a yan tabi awon ti a dibo yan lawujo tabi awon ti o dije fun iru ipo bee;

(d) faili ati iwifun ara eni ti o je mo olubeere, awon ti n pe akosile, awon ti n funni ni iwe ase ti ijoba tabi ile ise ijoba ti o ni ajosepo egbe ti ise ti eniyan yan laayo.

(e) iwifun ti a beere lowo eni ti o nsan owo ori nipa igbeyewo tabi gbigba eyikeyi ninu owo ori ayafi ti ofin ba fowo si;

(ẹ) iwifun ti o ro mo olufisun lori oro iwifun eto iwadii iwa odaran nipa eyikeyi ninu ile ise oluwadii iwa odaran.

(2). Ile-ise ijoba lee se afihan iwifun ti o jo mo ara eni ti:

(a) eni ti a ba fe se iwifun nipa re ba gba; tabi

(b) iru iwifun bee ba wa larowoto ni awujo

(3). ifihan eyikeyi ninu iwifun ti a toka si ninu isori yii yoo ba se anfaani fun awujo ati ti anfaani naa ba ju ti enikeni ti iru iwifun bee je mo, ile ise ijoba yoo fi iru iwifun bee han gege bi isori kerinla, ese keji ofin yii se so 14 (2).

15. (1) Ile ise ijoba yoo ko ibeere fun iwifun ti o ba je mo:

(a) asiri ti o jo mo owo, tabi ti o je mo isuna ti a gba lowo enikan tabi okun owo ti o ni asiri ti o si je pe ti a ba se iwifun re yoo ko wahala ba eni keta, yato si eyi ko si idi ti a ko fi le se afihan iwifun;

(b) ifihan iwifun ti o le se ijamba fun iduna dura ti o wa laarin enikan ati eniketa;

(d) idamoran ati ipe fun ise adehun ati iwifun ti o je pe ti a ba fihan le fa agabagebe tabi ojusaju.

(2) Ile ise ijoba lee ko lati fi iwe iranti han ti iru iwe iranti bee ba jo mo ayewo agbegbe ti ile ise ijoba se tabi ti a se fun-un lai wo atun pin si isori (1)

(3) Nigba ti ile ise ijoba ba ti se afihan iwifun tabi abala iwifun ti o je mo ayewo agbegbe, yoo pon dandan ki a pese akosile ilana ti a gba se ayewo ohun.

(4) Ile ise ijoba lee se afihan iwifun ti o wa ni ipin si isori (kinni) ti isori yii ti iru iwifun bee yoo ba se awujo lanfaani gege bi ilera awujo, aabo awujo tabi idaabo bo agbegbe paapaa ti o ba rii pe anfaani ifihan iwifun bee tewon ju adehun tabi ere ti adehun naa lee muwa lo tabi iduna dura pelu eni keta.

16. Ile ise ijoba lee ko lati fi iwifun ti o ba ro mo anfaani wonyi han ni:

(a) awon amofin ati onibara won;

(b) awon eleto ilera ati onibara won

(d) anfaani asiri oniroyin;

(e) anfaani ti ofin ba gba laaye fun awon onisemose.

17. Ile ise ijoba le ko lati se ifihan iwifun ti o je mo ise tabi iwadi ti awon igbimo eka eko won ba se

18. Laisi ani ani, eyikeyi ninu ofin yii ti a ba ti beere fun iwifun lowo ile ise ijoba lori oro ti ofin ya soto fun afihan ile ise ijoba bee yoo se afihan eyi ti a ko ya soto pe a ko gbodo fihan.

19. (1) Ile ise ijoba lee ko lati se ifihan iwifun ti o ba je mo:

(a) ibeere, idanwo tabi idahun si ibeere idanwo ti o je mo eko ti a n fi mo ikunjuwon eni tabi ti a fi n mo boya eniyan to si ise kan;

(b) aworan ile ti ayaworan ile tabi onimo ero ya ti a ko si fi owo ijoba ko ati eyi ti a fi owo ijoba ko sugbon ti iru ifihan bee le se akoba fun aabo;

(d) awon iwe-iranti ati iru ise bee ti o wa ni ile iyaweka (Library) ti o le fi awon ti o n kawe nibe han.

(2) Bi o ti wu ki o ri, gege bi a ti koo ninu isori yii, ibeere fun iwifun ni a ko ni sai dahun si ti anfaani ara ilu ba tewon ju aburu ti ifihan iwifun naa le se.

20. Enikeni ti o ba beere fun iwifun sugbon ti a ko fun-un, ni eto lati lo si ile ejo laarin ogbon ojo (30 days) lehin igba ti ijoba ko ti daa lohun ibeere re tabi laarin ojo ti ile-ejo lee so saaju leyin ogbon ojo.

21. Gbogbo ibeere ti a ba se ninu isori ogun yii (section 20) ni a o gbo ti a o si so ni soki.

22. Bi o ti wu ki o ri, eyikeyi ti o ba yato ninu ofin eri (Evidence Act) tabi ilana kan ti a se labe re, ile ejo ninu ijokoo re le, lori ibeere isori ogun (section 20) ofin yii se ayewo iwifun ti ofin yii ro mo ti o si wa labe ile iseijoba, ti a ko si gbodo fi iru iwifun bee pamo fun ile-ejo tabi iru re.

23. Ni gbogbo ijoko ile-ejo lori ibeere ninu isori ogun (section 20) ile-ejo yoo se akiyesi pelupelu igba ti o ye, igba wo ni a gba ikosile ati sise agboye ati ilo lati pe ki ile ejo tabi enikeni ma baa so iwifun tabi nnkan elo lona to je wipe a o fi so pe ki ile ise ijoba lo se afihan iwifun ti a beere fun.

24. Ni gbogbo ijoko ile-ejo lori ibeere ti o wa lori isori ogun erongba lati fi idi re mule pe a paa lase pe ki ile ise ijoba ko ibeere fun iwifun tabi die

lara iwifun yoo je ipinu ile ise ti oro kan.

25. (1) Nigbakigba ti ile ise ijoba ba ko lati dahun ibeere fun iwifun tabi ara i wifun lori iwe ofin yii, ile ejo yoo pase pe ki ile ise naa se ifihan iwifun ti a

beere fun ti:

(a) ile ejo ba rii pe ko ye ki ile ise ijoba ko lati se ifihan iwifun;

(b) nibi ti ile ise ti ni ase sugbon ti ile-ejo gba wipe ile-ise ohun ko ni eri to lati ko ibeere naa;

(d) nibi ti ile-ejo ba ti rii wipe anfaani ara ilu ti a ba se ifihan iwe-iranti ju ere ti a le ri ti a ko ba fi iwe naa han.

(2) Gbogbo ase ti ile ejo ba pa lori isori yii le duro lori idi wonyi abi bi ile-ejo ba se roo si.

26. Iwe ofin yii ko ba awon wonyi wi:

(a) awon atejade ti a se fun rira ara ilu;

(b) awon iwe Ile-Ikawe, tabi ile nnkan isenbaye ti a pese fun imulo ara ilu;

(d) awon nnkan ti a ko sile ikawe gbo-gbo-gbo tabi awon nnkan isenbaye gbo-gbo-gbo tabi awon nnkan ti kii se ti ijoba ti o wa nibe nipa enikan tabi egbe kan yato si ijoba.

27. (1) Ni abe ofin yii osise ijoba kan, tabi enikan ti o nsoju ile ise ijoba kan ti o ba

fi iwifun otito han si gbangba ni a ko le pe ni ejo si ile ejo labe ofin yowu ti o ti wa saaju ofin yi, iba je ofin odaran, ofin ifiyajeni, ofin asiri ijoba tabi ofin kofin imiran, niwon igba ti o ba ti je wipe ofi iwifun naa han pelu okan otito.

2) Ko si ohunkohun ti o wa ninu ofin odaran tabi ofin asiri ijoba ti yio le pa osise oba lara ti o ba fi iwifun otito han si gbangba lori laigbase niwon igba ti o ba ti je wipe osise bee ni igbagbo wipe iwifun naa yio se afihan:

(a) riru ofin tabi titako ilana;

(b) isowo oba basubasu, ikowoje tabi asilo ipo;

(d) ohun ti o je ewu fun ilera ati abo ara ilu, bi o tile je wipe o fi iwifun naa han ni lori titele ilana ofin ominira iwifun yii.

(3) a ko si le pe enikeni ti osise ijoba ba fun ni iwifun yi tabi eni ti o tun nse itankale iwifun naa lejo.

28. (1) Ni tooto, awon akosile ijoba kan ni o je oun asiri ti a si fi si ipamo to ni aabo to peye, sugbon eyi ko da fifi iwifun lori won han si gbangba duro niwon igbati a ba ti kowe bere iru akosile bee lowo ile-ise oun gege bii alakale ofin yi. Iru ile ise bee ni o leto lati ye iru iwifun bee wo boya o je awon eyi ti a ti fenukan ni ese kokanla titi de ikokanlelogun ninu ofin yii.

(2) Ti iru ile ise bee ba ti ti ri wipe iwifun naa kii se iru eyi ti a fenuba ipin si isori kinni ese ofin yi, ile ise naa yi o yonda iru iwifun ti a bere fun yi.

(3) Ti iru ile ise bee ba ta ri wipe iru akosile ti a fenuba ni ipin si isori kinni ese yi ni a n beere fun iwifun lori re, ile ise naa yoo se afiye eyi fun eni ti o nbere iwifun naa.

29. (1) O pe ju, ni ojo kinni osu keji odun ni gbogbo ile ise ijoba gbudo maa fi

irohin ohun ti o sele lodun ti o koja ni ile ise won sowo si agbejoro agba patapata ni orile ede yii lori awon akori wonyi:

(a) oye ibere fun iwifun melo ti ile ise naa gba wipe ko ba ilana ibere fun iwifun mu ati idi ti ile ise naa fi gba bee;

(b) oye ejo kotemilorun ti awon eniyan pe labe ofin yii ati idi ti ile ise naa fi gbese le ikokan ninu iwifun ti a pejo si;

(d) alaye boya ile ejo faramo gbigbesele iwifun ti ile ise naa se ati alaye soki lori iru iwifun ti ile ise naa gbesele;

(e) oye iwe ibere fun iwifun ti o wa nile ti ile ise ijoba ko itii sise le lori ni ogbonjo o lekan osu kewa odun ti o koja lo ati oye ojo ti iru iwe bee ti wa ni ile ise naa lai sise le lori;

(ẹ) oye iwe ibere fun iwifun ti ile ise naa ti ri gba ati oye iwe ibere ti ile ise naa ti sise le lori;

(f) oye ojo ti o gba ile ise ijoba lati sise lori oniruuru iwe ibere fun iwifun;

(g) apapo oye owo ti ile ise naa gba lati sise lori awon iru iwe ibere fun iwifun bee;

(gb) oye ojulowo osise ile ise ijoba ti o nsise lori awon iwe ibere fun iwifun ati apapo oye owo ti ile ise naa ni lati sise lori iru awon iwe ibere bee.

(2) Iru irohin yi ni ile ise ijoba kookan yi o je ki o wa ni arowoto arailu nipase ero ayarabiasa tabi ero ibanisoro ayelujara, ero amohunmaworan, ero asoromagbesi tabi ona ero miran.

(3) Agbejoro agba yi o je ki iru awon irohin wonyi ti ile ise ijoba ba fi sowo sii wa ni arowoto ara ilu lori ero kayelujara tabi ninu iwe ti o se ti o ko awon irohin wonyi papo.

(4) Agbejoro agba naa yoo fi to omo ile igbimo asofin apapo kekere ti o je alaga igbimo atunse ijoba ati omo ile igbimo asofin apapo agba ti o je alaga igbimo lori oro ijoba ati idajo, iru awon irohin ile ise ti o ti rigba o pe ju osu kerin odun ti a ko irohin wonyi, yi o si rii wipe oun je ki akojopo irohin bee te won lowo yala gegebi iwe tabi nip a ero ayelujara.

(5) Agbejoro agba yio seto itonisona ti o to ni oju re lori bi agbekale irohin ati sise daadaa labe ofin ominira iwifun.

(6) Ojuse agbejoro agba ni lati ri wipe gbogbo ile ise ti oro ofin yi kan ni o tele ilana ofin yii.

(7) Ki o to di ojo kini osu kerin ni odoodun ni agbejoro agba yi o ti fi irohin odun ti a lo tan ranse si ile igbimo asofin apapo eyi ti yio salaye oye ejo ti o waye labe ofin yi, ibi ti a fori awon ejo naa ti si, oye owo ti ejo naa na ile ise ijoba, oye owo ti ile ise pa ati awon ijiya ti o waye.

(8) Iru irohin yi gbudo safihan ipa ti ile ise eto igbejo ti se lati je ki ijoba ati ile ise ijoba tele ilana ofin yii

(9) Fun ese ofin yi, awon itumo wonyi se koko:

(a) "Ijoba" je gbogbo ile ise oba, ti ologun titi kan ile ise aare ori ile ede ati gbogbo eka ijoba yala o daduro ni tabi ko da duro

(b) "Iwifun" je oro yowu ti a ko ninu ofin yi fun akosile tabi iwe ti o da lori isejoba, eyi ti ile ise ijoba ko pamo yala gege bii iwe akosile tabi lori ero.

30. (1) Ofin yi wa lati kin awon ofin ti o ti wa tele lehin. Kii ise lati se ayipada

awon eto si iwifun tabi iwe iranti oro ijoba. Ko si wa lati sadinku arowoto oniruru iwifun`oro ijoba ti o ti wa teleri.

(2) Nibi ti ibere lori boya akosile ijoba kan ye lati fi si arowoto fun eni ti o ba bere fun batun waye, idahun re ni a gbudo fi ori re ti ni ibamu pelu alakale ofin yii, ayafi akosile ijoba ti ofin yi ba yo sile kuro lara eyi ti o ye ki o wa ni arowoto ara ilu.

31. Ninu ofin yi:

"Olubere" je eni ti o kowe bere fun iwifun tabi iwe iranti oro ijoba;

"Iwe ibere" je iwe ti a ko lati fi beere fun iwifun oro ijoba;

"Ile Ejo" je ile ejo giga ti ijoba apapo;

"Ile Okeere" je orile ede ti o yato si Naigiria;

"Iwifun" je gbogbo akosile, iwe, fonran ti a gba ohun si, afihan

alaworan, igbohunsile ati beebee lo.

"Ile Ise Ijoba" je gbogbo eka isejoba lori isofi, idajo iseto ijoba, ajo  ijoba, igbimo ijoba ati gbogbo ibi ti osise ijoba ba ti n sise ti o si je wipe owo ara ilu ni won maa sise won.

"Akosile gbogbogbo" je akosile yowu ti a gbekele ti a gba, ti a ni tabi ti a lo labe akoso ile ise ijoba tabi ti aladani eyi ti o kan oro ti o je gbogbo mutumuwa logun lara re ni:

**(a)** **akosile** lori ohun elo yowu**;**

(b) ape, tabi akosile miran ti o safihan tabi salaye ohunkohun eyi ti ounje ikan lara re tabi eyi ti o je atamo si ni onakona;

(d) iwifun ti a gbe pamo sori ero

(e) iwe tabi aworan;

(ẹ) ise tabi aworan

"Alakoso ile ise ijoba" ti oro iwifun ati irohin kan.

"Eniyan" je eyo enikan, egbe, akojopo eniyan, lajolajo tabi agbo eniyan.

"Iwifun ara eni" je iwifun ijoba ti a gba lori enikan ti a damo sugbon ti ko ni nkankan se pelu ojuse re lenu ise ijoba.

32. A le pe ofin yi ni ofin Ominira iwifun ati Irohin ti egbewa odun o le mokanla.

I CERTIFY, IN ACCORDANCE WITH SECTION 2 (1) OF THE ACTS AUTHENTICATION ACT, CAP. A2, LAWS OF THE FEDERATION OF NIGERIA 2004, THAT THIS IS A TRUE COPY OF THE BILL PASSED BY BOTH HOUSES OF THE NATIONAL ASSEMBLY.

SALISU ABUBAKAR MAIKASUWA, mni
CLERK TO THE NATIONAL ASSEMBLY

27th DAY OF MAY, 2011.

27

Mo jeri wipe ni ibamu pelu ipin si isori keji ti ipin(1)Ofin "A" keji (Cap.A2) ti ile Naijiria fun odun kerinle lelegbewa (2004), wipe iwe ofin yii jee otito ni itewo gba lati owo ile igbomo asofin mejeeji ti ile Naijiria.

Salisu Abubakar Maikasuwa (mni)
Akowe asofi apapo.
Ojo ketadinlogbon osu karun –
egbewa odun le mokanla

**Schedule to Freedom of Information Bill, 2011**

| SHORT TITLE OF THE BILL | LONG TITLE OF THE BILL | SUMMARY OF THE CONTENTS OF THE BILL | DATE PASSED BY THE SENATE | DATE PASSED BY THE HOUSE OF REPRESENTATIVE |
|---|---|---|---|---|
| **Freedom of Information Bill, 2011** | An Act to make public records and information more freely available, provide for public access to public records and information, protect public records and information to the extent consistent with the public interest and the protection of personal privacy, protect serving public officers from adverse consequences for disclosing certain kinds of official information without authorization and establish procedures for the achievement of those purposes and; for related matters. | This Bill seeks to make public records and information more freely available, provide for public access to public records and information, protect public records information to the extent consistent with the public interest and the protection of personal privacy, protect serving public officers from adverse consequences for disclosing certain kinds of official information without authorization and establish procedures for the achievement of those purposes. | 24th May, 2011 | 24th May, 2011 |

I certify that this Bill has been carefully compared by me with the decision reached by the National Assembly and found by me to be true and correct decision of the Houses and is in accordance with provisions of the Acts Authentication Act Cap, A2, Laws of the Federation of Nigeria, 2004.

I ASSENT.

**SALISU ABUBAKAR MAIKASUWA, mni**
**Clerk to the National Assembly**
**27th Day of May, 2011**

**DR. GOODLUCK EBELE JONATHAN, GCFR**
**President of the Federal Republic of Nigeria**
**28th Day of May, 2011**

| KORI KEKERE | AKORI GBOORO | ASO LEREFE IPESE OFIN YI | IFOWOSI AWON ASOFIN |
|---|---|---|---|
| Ominira Iwifun ti egbewa odun ole mokanla | | Ofin lati je ki iwifun oro isejoba wa ni arowoto gbogbo eniyan, lati daabo bo iwifun, ona isejoba ni ibamu pelu ife ara ilu ati lati daabo bo osise ijoba lori ewu ti o le jeyo nipa fifi iwifun oro ijoba si arowoto ara ilu. | Ojo kerindinlogun osu karun egbewa odun ole mokanla. |

Mo jeri wipe mo ti se afiwe ofin yi pelu ipinnu ile asofin apapo lori re ti mo si rii pe ofin naa wa ni ibamu pelu ipinnu awon asofin ni ibamu pelu Ofin “A” keji (Cap.A2) ti Naijiria fun odun kerinle lelegbewa (2004)

Mo fi owo si :

Salisu Abubakar Maikasuwa (mni)
Akowe asofi apapo.
Ojo ketadinlogbon osu karun –
egbewa odun le mokanla

Dr. Goodluck Ebele Jonathan, GCFR,
Aare Orile Ede Naijiria
Ojo keji dinlogbon, osu karun-
Egbewa odun le mokanla

Contact:
Plot 3685 Erie Close,
Off Erie Crescent, Off Nile Street
Maitama, Abuja- Nigeria
Tel: +234 9 7802227
info@r2knigeria.org
www.r2knigeria.org